Mo fi ẹni ti ẹmi mi n bẹ lọwọ Rẹ bura, o maa ku díẹ ki ọmọ Maryam sọkalẹ si aarin yin ni adajo olusẹdeedee, ti o maa run agbelebuu, ti o maa pa ẹlẹdẹ, ko nii jẹ ki wọn san isakọlẹ mọ, ti owo maa pọ titi ẹni kankan ko fi nii gba a mọ

Lati ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: "Mo fi ẹni ti ẹmi mi n bẹ lọwọ Rẹ bura, o maa ku díẹ ki ọmọ Maryam sọkalẹ si aarin yin ni adajo olusẹdeedee, ti o maa run agbelebuu, ti o maa pa ẹlẹdẹ, ko nii jẹ ki wọn san isakọlẹ mọ, ti owo maa pọ titi ẹni kankan ko fi nii gba a mọ".
[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n bura lori sisunmọ sisọkalẹ Isa ọmọ Maryam- ki ikẹ Ọlọhun maa ba a- lati maa sẹ idajọ laaarin awọn eniyan pẹlu deedee pẹlu Sharia ti Muhammad, Ati pe o maa pada run agbelebuu ti awọn Nasara n gbe tobi, Atipe Isa- ki ikẹ Ọlọhun maa ba a- maa pa ẹlẹdẹ, Ati pe Isa- ki ikẹ Ọlọhun maa ba a- ko nii jẹ ki wọn san isakọlẹ mọ, o si maa jẹ ki gbogbo èèyàn wọnú Isilaamu. Ati pe dajudaju owo maa pada maa da ti ẹni kankan ko nii gba a; ìyẹn maa rí bẹ́ẹ̀ fun pipọ rẹ, ati rirọrọ gbogbo ẹni kọọkan pẹlu nnkan ti o n bẹ ni ọwọ rẹ mejeeji, ati sisọkalẹ alubarika ati itẹle-ara-wọn awọn oore.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/65025